# ÌLỌSÍWÁJÚ ÈDÈ YORÙBÁ ÀTI IPA TÍ ÌMỌ̀ ẸRỌ Ń KÓ LÓRÍ RẸ̀

Ọládiípọ̀ **AJIBÓYÈ** (*Ph.D., FACLS/AHP, MNAL, MNITI*)
Yunifásítì ti Èkó
oajiboye@unilag.edu.ng

**DOI : https://doi.org/10.5281/zenodo.20757966**

**Àṣamọ̀**
Àpilẹ̀kọ yìí ṣe àyẹ̀wò ìlọsíwájú tó ti dé bá èdè Yorùbá àti ipa tí ìmọ̀ ẹrọ ń kó lórí ìdàgbàsókè rẹ̀ lóde òní. Èdè tó bá ti di kíkọ sílẹ̀ tí a sì ń lò láti fi kọ́ni lẹ́kọ̀ọ́ ti di gbájúgbajà èdè. Ẹ̀rí tó dájú wà wí pé Yorùbá ti wà lákọsílẹ̀ látọjọ́ tó ti pẹ́, a sì ti bẹ̀rẹ̀ sí kẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀ ní ilé ìwé ní gbogbo ìpele ètò ẹ̀kọ́ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà láti ọdún gbọọrọ. Ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, láti mú kí ó rọ́rùn ní kíkọ́ fún akẹ́kọ̀ọ́ àti olùkọ, akitiyan díẹ̀ ni ìjọba, àwọn olórí ilé ẹ̀kọ́ àti àwọn olùkọ́ sà láti pèsè àwọn èròjà ìkọ́ni tó yẹ ní lílò. Ṣùgbọ́n lóde òní, àwọn èròjà ọjọ́un wọ̀nyẹn, bí wọ́n tún ti kéré tó, wọn kò wúlò mọ́. Bí ayé bá yí, ṣe ló yẹ̀ ká báyé yí. Ohun tí àpilẹ̀kọ yìí dojúkọ ni èdè Yorùbá àti àmúgbòòrò rẹ̀ pàápàá lórí abala tó jẹ mọ́ ìmọ̀ ẹrọ. Mo wo ìṣàmúlò oríṣiríṣi ìmọ̀ ẹrọ ìgbàlódé, ìṣàmúlò ìtàkùn àgbáyé láwùjọ Yorùbá àti bí wọ́n ṣe ń mú ìtẹ̀síwájú bá èdè náà. Lára àwọn ohun ti mo gbé ṣe nínú pépà náà ni àmúgbòòrò kíkẹ́kọ̀ọ́ Yorùbá. Mo ṣàfihàn rẹ̀ pé yàtọ̀ sí yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́, àwọn ìtàkun ayélujára tàwọn lájọlájọ àti tàdáni ló ti wà ní àrọ́wọ́tó tí wọ́n sì ti ń kọ́ ẹ̀lẹ́kajẹ̀ka ẹ̀kọ́ Yorùbá. Mo tún ṣe àfihàn àti àlàyé rẹ̀ pé oríṣiríṣi àmúlò àwọn ẹrọ bí èyí tó ń ṣògbufọ̀ sí èdè Yorùbá, ẹrọ ìwé atúmọ̀ èdè Yorùbá, áàpù tó ń kọ́ni ní èdè Yorùbá b.a. mesmerise, duolingo, Yoruba101 abbl. ni ó ti wà ní àrọ́wọ́tó olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́. Lẹ́yìn náà ni mo sọ nípa ìwúlò àti ìtẹ̀síwájú tí àwọn ìkànni ìkọ́ni àti èròjà aápù ti mú bá ẹ̀kọ́ Yorùbá àti ìdàgbàsókè rẹ. Mo wá tẹ̀síwájú láti wo ọṣẹ́ tí àmúlò àwọn ẹrọ àti oríṣiríṣi áàpù ń ṣe èdè náà. Ní ìgúnlẹ̀, mo pàrọwà sí ìjọba, àwọn lájọlájọ, àti àwọn ilé ìwé, bóyá ti ìjọba àbí àdáni láti ṣe àtìlẹyìn tó tó fún ìpèsè àwọn èròjà ẹ̀kọ́ túntun wọ̀nyí ní ilé ìwé gbogbo láti mú kíkọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá túbọ̀ rọrùn, kó sì gbòòrò si, kí àwa tí a jẹ́ olùkọ́ má sun àsùnpiyè lórí ohun tó ń lọ lórí ìkànnì ayélujára lórí bí kíkọ́ àti kíkọ èdè Yorùbá fi di irú wá, ògìrì wá.

## 1. Ìfáàrà

Èdè lápapọ̀ jẹ́ ohun àdáni pàtàkì tí Olódùmarè dá mọ́ ènìyàn tí wọ́n fi yàtọ̀ sí ẹranko. Òhun[1] ni ohùn ẹnu tí a fi ń ṣe àsọyé àti àgbọ́yé láàárín àwọn elédè kan. Èdè yìí kan náà ni a fi ń ronú tí a fi ń gbé èrò ọkàn ẹni jáde. Òhun gan-an ni orísun ìdanimọ̀ pàtàkì tí ó lágbára jù tí a lè fi dá ẹ̀yà kan mọ̀ yàtọ̀ sí ẹ̀yà mìíràn. Àsomọ́ kan tó níí ṣe pẹ̀lú ẹ̀yà ni èdè jẹ́. Ìyẹn ni wí pé, tí a bá sọ pé ẹ̀yà Hausa, ẹ̀yà Ìgbò, ẹ̀yà Nupe, a kò le yà wọ́n kúrò lára èdè wọn. Èyí gan-an ló fà á tí a fi ní èdè Hausa, èdè Ìgbò, èdè Nupe, àti èdè Yorùbá. Èdè tún ni ọ̀nà tí a lè gbà pa àṣà, ẹ̀sìn àti ìṣe ẹ̀yà kan mọ́ láti ìran kan dé ìran mìíràn. Ohun tí àpilẹ̀kọ yìí dojúkọ ni èdè Yorùbá àti àmúgbòòrò rẹ̀ pàápàá láti igun tó jẹ mọ́ ìmọ̀ ẹrọ.

[1] Nínú àwọn iṣẹ́ tí mo ti ṣe lórí àkọtọ́, b.a. Ajiboye (2024), mo ti dá àbá wí pé kí a máa kọ ọ̀rọ̀ arọ́pò orukọ enìkẹta gígùn sílẹ̀ pẹ̀lú kọ́nsónáńtì "h". Èyí ló máa mú kí ó dọ́gba pẹ̀lú àwọn ojúgbà rẹ̀ tókù: èmi, ìwọ, àwa, ẹ̀yin, àwọn.

**2. Ìlàkàkà sísọ èdè Yorùbá di kíkọsílẹ̀**
Kí a tó bẹ̀rẹ̀ sí sọ nípa ìlọsíwájú èdè Yorùbá pàápàá tó jẹ mọ́ ìmọ ẹ̀rọ, a gbọ́dọ̀ mẹ́nuba ìbẹ̀rẹ̀ èdè Yorùbá àti akitiyan àwọn ènìyàn àti lájọlájọ.

Ìlàkàkà àkọ́kọ́ ni sísọ èdè Yorùbá di kíkọsílẹ̀ ṣáájú kí orílẹ̀ èdè Nàìjíríà tó wà, àti ipa tí àwọn òyìnbó kó. Ohun tí a fẹ́ fi bẹ̀rẹ̀ ni wí pé ṣáájú kí orílẹ̀ èdè Nàìjíríà tó wà ni oríṣiríṣi akitiyan kíkọ Yorùbá sílẹ̀ ti bẹ̀rẹ̀. Láìní fepo bọyọ̀, ipa àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun yìí kò kéré. Lórílẹ̀ èdè Sierra Leone ni àwọn ajíyìnrere aláwọ̀funfun ti bẹ̀rẹ̀ àmúlò Yorùbá ni 1825, kó to di pé àkọtọ́ wà fun ní ààrín ọdún 1848 sí 1849 níbi àpérò kan ní London (Awóbuluyi 2012). Tí a bá fẹ́ fi ojú ọ̀làjú wò ó, ọ̀nà méjì ni èdè pín sí. Àwọn ni aláfẹnusọ àti alákọsílẹ̀. Ìsọ-Yorùbá-di-kíkọsílẹ̀ yìí ló sọ́ di ọmọ ẹgbẹ́ èdè alákọsílẹ̀ àti èdè ọ̀làjú, yàtọ̀ sí èdè aláfẹnusọ nìkan. Èdè ọ̀làjú jẹ́ èdè tí a ń lò dánilẹ́kọ̀ọ́, ṣe káràkátà àti fi wàásù láti jèrè ọkàn àwọn ènìyà àwùjọ elédè náà. Èdè ọ̀làjú ni èdè tó kọjá ilẹ̀ àwọn tó lèdè náà. Èdè tí tonílétàlejò ń sọ ni.

Ìlàkàkà kejì ni akitiyan ìjọba ìpínlẹ̀ ìwọ̀ oòrun tí ó ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìgbìmọ̀ tó máa ṣe àkójọ èdè-ìperí fún ètò ẹ̀kọ́. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní bí òǹkọ ò kọ, kí lòǹgbìn ó gbìn. Akitiyan àwọn ẹni bí ẹni, ènìyàn bí ènìyàn lórí àtimú kí ète ìjọba ìgbà náà júṣe kò ṣeé fojú fò dá tàbí fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn. Lára wọn ni Olóyè I.O. Délànọ̀, D.O. Fágúnwà, J.F. Ọdúnjọ, Olóyè T.A. Awoniyi, ní ìdàgbàsókè Yorùbá, Ọ̀jọ̀gbọ́n Adéboyè Babalọlá, Ọ̀jọ̀gbọ́n Babs Fáfunwá, Ọ̀jọ̀gbọ́n Olúdáre Ọláàjubù, Ọ̀jọ̀gbọ́n Fẹ̀yìntì Ayọ Bámigbóṣé, Ọ̀jọ̀gbọ́n Fẹ̀yìntì Ọládélé Awóbùlúyì, Ọ̀jọ̀gbọ́n Fẹ̀yìntì Awoniyi, abbl. Ipa ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n kó. Olóyè I.O. Délànọ kọ ìwé atúmọ̀ èdè Yorùbá, bẹ́ẹ̀ ló tún kọ ìwé Ìtàn Àròsọ b.a. Lọ́jọ́ Ọjọ́'un àti Ayé D'ayé Òyìnbó. D.O. Fágúnwà ni ó kọ́kọ́ kọ ìwé ìtàn Àròsọ tó pọ̀ jù. Àwọn ìtàn àròsọ rẹ̀ tó jẹ́ gbajúgbajà ni: Ògbójú Ọdẹ nínú Igbó Irúnmọlẹ̀, Igbó Olódùmarè, Ìrìnkèrindò nínú Igbó Elégbèje, Ìrèké Oníbùdó àti Àdììtú Olódùmarè. Olóyè J.F. Ọdúnjọ tún jẹ́ òǹkọ̀wé pàtàkì tí ó kọ ìwé Aláwìyé Apá Kìíní -Aláwìyé Apá Kẹfà fún àmúlò ní ilé ìwé alákọ́bẹ̀rẹ̀. Ọ̀jọ̀gbọ́n Adéboyè Babalọlá, àti Ọ̀jọ̀gbọ́n Olúdáre Ọláàjubù kó ipa pàtàkì lórí sísọ ewì alohùn di àkọsílẹ̀ tí a sì ń kọ́ nílé ìwé gbogbo. Ẹ̀wẹ̀, akitiyan Ọ̀jọ̀gbọ́n Fẹ̀yìntì Ayọ Bámigbóṣé, Ọ̀jọ̀gbọ́n Fẹ̀yìntì Ọládélé Awóbùlúyì, Ọ̀jọ̀gbọ́n Fẹ̀yìntì T.A. Awoniyi nínú ìpèsè èdè-ìperí àti gírámà Yorùbá tó kún. Eégún ńlá tí ń kẹ́yìn ìgbàlẹ̀ ni Ọ̀jọ̀gbọ́n Babs Fáfunwá tóhun náà ṣe gudugudu méje, yààyà mẹ́fà, nínú gbígbé èdè abínibí lárugẹ àti nínú ìkọ́ni wọn nílé ìwé alákọ́bẹ̀rẹ̀.

**3. Ìlọsíwájú èdè Yorùbá**
Ipa tí èdè ń kó láti fi ìmọ̀ àti òye yéni kò kéré. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní, aṣọ ìgbà la ń dá fún ìgbà. Èdè a máa dàgbàsókè, a sì máa gbèrú si. Oríṣiríṣi ipele gírámà èdè ni ìdàgbàsókè àti àyípadà ti máa ń wáyé. Ọ̀kan lára pele tí ìdàgbàsókè ti máa ń wáyé ni àká ọ̀rọ̀. Nínú àká ọ̀rọ̀ Yorùbá, mo ṣe àkíyèsí pé ní ǹkan bí ogún ọdún sẹ́yìn, àwọn ọ̀rọ̀ tàbí àpólà ọ̀rọ̀ kan tó wà nínú èdè náà lónìí kò sí nínú àká ọ̀rọ̀ Yorùbá rárá nígbà náà. Kódà tí a bá wo ìtumọ̀ tí àwọn ọ̀rọ̀ kan ní lónìí, kí a fi wé òye tí wọ́n ní ṣáájú àsìkò yìí, wọ́n jìnnà síra wọn púpọ̀. Ọ̀nà méjì ni àyípadà náà pín sí: àwọn kan ti ṣe àmúgbòrò ìtùmọ̀ ọ̀rọ̀ inú ède Yorùbá, àwọn kan sì ti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ tuntun. Díẹ̀ nínú àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ nìwọ̀nyí: **já mi si**, **já pa**, **jẹun sókè**, (má) **gbe mọ́ra**, **mà á jojú** ẹ̀, **mà á tẹ̀ ẹ́ lójú mọ́lẹ̀**, **ganu si**.

Àkíyèsí mìíràn ni wí pé ipò èdè a máa yípadà. Àwọn èdè kan tó jẹ́ pé ní ọjọ́'un àná, a kì í lò wọ́n ju ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀ lááàrín àwọn elédè yẹn nìkan lọ, ṣùgbọ́n tó sì jẹ́ pé lẹ́yìn sáà kan, àmúgbòòrò á ti dé bá irú èdè bẹ́ẹ̀ débi pé wọ́n ti lè di mímúlò létò ẹ̀kọ́, ọrọ̀ ajé, abbl. Lọ́jọ́'un àná, ipò sísọ lẹ́nu nìkan lááàrín àwọn elédè nìkan ni Yorùbá wà. Ṣùgbọ́n èdè náà ti gòkè àgbà, ó ti di àmúlò níbi gbogbo fún ohunkóhun tí a ń fi èdè tí ọ̀làjú ti dé bá ṣe.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé òfin ìjọba àpapọ̀ tó jẹ mọ́ ètò ẹ̀kọ́, ipò àti ìlànà àmúlò àwọn èdè abínibí ní ilé ẹ̀kọ́ alákọ̀bẹ̀rẹ̀ wà, síbẹ̀ ọwọ́ dẹgbẹrẹ tí ìjọba àpapọ̀ fi mu náà ni àwọn ìjọba ìpínlẹ̀ fi mu. Ẹ jẹ́ ká ránra wa létí pé, òfin ìjọba lórí kíkọ́ èdè Yorùbá ní ilé ìwé alákọ̀bẹ̀rẹ̀ àti girama fàyè gba èdè abínibí bí èdè àmúlò fún kíkọ́mọ ní gbogbo ẹ̀kọ́ yàtọ̀ sí èdè Gẹ̀ẹ́sì, tó sì kàn án nípá kí ọmọ kọ́ èdè abínibí kan, ó kéré tán, láti ọdún kẹ́rin ilé ìwé alákọ̀bẹ̀rẹ̀ títí ìparí ẹ̀kọ́ ní ilé ìwé girama. Ó ṣeni láàánú wí pé, ajá òyìnbó dára, ṣùgbọ́n ó ku àtifiṣọdẹ! Òfin náà dára nítòótó, ṣùgbọ́n ó ku àtimúlò rẹ̀. Ó ṣeni ní àànú, ó sì bani lọ́kàn jẹ́ pé Mínísítà ètò ẹ̀kọ́ lọ́wọ́lọ́wọ́, Ọ̀mọ̀wé Ọlátúnjí Aláusá ti sọ pé kí wọ́n fagi lé àmúlò èdè abínibí gẹ́gẹ́ bí èdè àfikọ́mọ́ ní ọdún mẹ́ta àkọ́kọ́ ní ilé ìwé alákọ̀bẹ̀rẹ̀, kó sì bọ́ sí ipò ẹ̀kọ́ kan lásán!

Bí ọ̀rọ̀ tilẹ̀ rí báyìí, ọlọ́tọ̀ ní tòhun ọ̀tọ̀; ìjọba Èkó dà bí ẹni pé ó yàtọ̀. Ní bí ọdún méjìlá tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ sẹ́yìn ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí ní ṣe àmúlò èdè Yorùbá nílé ìgbìmọ̀ aṣòfin lójọọjọ́ ọjọ́bọ̀. Odidi ọjọ́ mẹ́ta ni olùkọ́ ẹ̀ka Ìmọ̀ ẹ̀dá èdè, Ilẹ̀ Áfíríkà àti Aṣíà ti Yunifásítì Èkó àti olùkọ́ kan ní LASU fi ṣe ìdánilẹ́kọ̀ fún àwọn ọmọ ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin ìpínlẹ̀ lórí èròjà tí wọ́n níí lò láti lè lo Yorùbá fún ìjíròrò wọn pẹ̀lú ìrọ̀rùn.

Ìlàkàkà ìjọba Èkó lórí àmúlò èdè abínibí kò parí sí àmúlò nílé ìgbìmọ̀ aṣòfin nìkan. Ni ọdún tó kọjá ni ìjọba Èkó tún ti ṣe àmúgbòrò àmúlò èdè àti àṣà Yorùbá ní ilé ẹ̀kọ alákọ̀bẹ̀rẹ̀ àti girama. Yàtọ̀ sí pé èdè Yorùbá pọn dandan fún gbogbo akẹ́kọ̀ọ́ ní ìpele ẹ̀kọ́ méjèèjì, àwọn olùkọ́ tún lè lo èdè Yorùbá láti ṣe àlàyé ẹ̀kọ́kẹ́kọ̀ọ́ tí wọ́n ń kọ́mọ tí kò bá yé wọn ní èdè Gẹ̀ẹ́sì. Ẹwẹ̀, àyè tún wà fún àmúlò èdè Yorùbá ní ilé iṣẹ́ ìjọba ní ìpínlẹ̀ náà lọ́jọ́kọ́jọ́. Pabanbarì rẹ̀ ni wí pé ní gbogbo ọjọ́rú ló di dandan kí gbogbo òṣìṣẹ̀ máa wọ aṣọ ìbílẹ̀ lọ síbi iṣẹ́ wọn, kódà ní àwọn ojọ́ tó kù láàárín ọ̀sẹ̀ àyè gbà wọ́n láti tún máa wọ aṣọ ìbílẹ̀ bákan náà.[2]

Ọ̀rọ̀ àmúlò èdè Yorùbá ní ìpínlẹ̀ Èkó kò pin sí ilé ẹ̀kọ́ alákọ̀bẹ̀rẹ̀ àti girama. Yunifásítì ìjọba Èkó, LASU náà ti fakọ yọ ní gbígbé Yorùbá láruge. Wọ́n ti sọ ẹ̀kọ́ Yorùbá di ẹ̀kọ́ gbogbogbò tí a mọ̀ sí General Studies (GST) tí gbogbo akẹ́kọ̀ọ́ yunifásítì náà gbọ́dọ̀ ṣe kí wọn si yege nínú ìdànwó rẹ̀. Tẹ́lẹ̀ la ti máa ń gbọ́ wí pé 'ajíṣe bí Ọ̀yọ́ làá rí, Ọ̀yọ́ kì í ṣe bí baba ẹnìkankan'. Àfàìmọ̀ kí a má yí ìpèdè yìí padà sí 'Ajíṣe bí Èkó làá rí, Èkó kì í ṣe bí baba ẹnìkankan'. Ní ìkádìí ìsọ̀rí yìí, ìbéèrè kan tó ń fẹ́ ìdáhùn ni èyí o: ibo ni àwọn Yunifásítì tókù wà nínú àmúlò èdè Yorùbá nínú ètò ẹ̀kọ́ wọn? Ó yẹ kí àwọn ìjọba ìpínlẹ̀ tókù tí a ti ń sọ èdè Yorùbá ṣe àwòkọ́ṣe ìpínlẹ̀ Èkó.

**4 Ipa tí ìmọ̀ ẹ̀rọ ń kó lórí ìlọsíwájú èdè Yorùbá**

Lẹ́yìn tí a ti sọ nípa ìbẹ̀rẹ̀ àti ìdìde èdè Yorùbá, ó yẹ kí a wo ìṣàmúlò oríṣiríṣi ìmọ̀ ẹ̀rọ, ìṣàmúlò ìtàkùn àgbáyé láwùjọ Yorùbá àti bí èyí ṣe mú kí ó rọrùn fún kíkọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá, èyí tó sì mú kí ìtẹ̀síwájú dé bá èdè náà. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní aṣọ ìgbà ni à ń dá fún ìgbà. Nítorí ìdí èyí, èdè Yorùbá náà gbọ́dọ̀ bá ìgbà yí bí àwọn èdè akẹgbẹ́ rẹ̀ tókù lágbàáyé nínú ìṣàmúlò ìmọ̀ ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà àti àwọn ọ̀kanòjọ̀kan èròjà inú rẹ̀ lóríṣiríṣi; fóònù àti àwọn ẹ̀rọ ìgbàlódé mìíràn abbl. Àwọn èdè àgbáyé kan ti wà tí àmúlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ti mú kí wọ́n lè ṣe ìṣohùndàkọsílẹ̀: ìyẹn kí ẹnìkan máa sọ̀rọ̀ jádé kí ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà máa tẹ̀ ẹ́ sílẹ̀, ìṣàkọsílẹ̀dohùn: ìyẹn yíyí ohun tí a kọ sílẹ̀ di ohùn ẹnu, ẹ̀rọ-ògbufọ̀: ìyẹn ẹ̀rọ tó ń túmọ̀ ọ̀rọ̀, gbólóhùn tàbí afọ̀ láti èdè kan sí èdè mìíràn, ẹ̀rọ akàwésínilétí: ìyẹn ẹ̀rọ tí ó lè máa ka ohun tó wà látẹ̀sínú-ìwé jáde gẹ́gẹ́ bí ohùn ẹnu, abbl. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé kì í ṣe gbogbo ẹ̀rọ wọ̀nyí ló ti wà ní àmúlò lédè Yorùbá, síbẹ̀ a rí nínú wọn tí àwọn onímọ̀ èdè àti onímọ kọ̀ǹpútà ti ń ṣe àmúlò rẹ̀.

[2] Ọmọ Ọba Adéṣínà àti Ọ̀mọ̀ Ibrahim Adéìígbé tí wọ́n jẹ́ olùkọ́ ní ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkó ló sọ èyí di mímọ̀ fún mi.

**4.1 Ìṣògbufọ̀ sí èdè Yorùbá àti ìmọ̀ ẹ̀rọ**
Èròjà kan pàtàkì fún ìṣògbufọ̀ pàtàkì ni oríṣiríṣi aápù bí Google Translate, Microsoft Translator abbl. Èyí sì ti mú ọ̀pọ̀ ìrọ̀rùn bá aáyan òbgufọ̀ ṣíṣe fún tawo tọ̀gbẹ̀rì. Èròjà ajẹmẹ́rọ mìíràn ni ìwé atúmọ̀-èdè orí ìtàkùn. Lára àwọn àbùdá tí a fi ń mọ èdè tí ó ti ní ìdàgbàsókè ni ìwé atúmọ̀-èdè ní èdè náà wà. Ọjọ́ pẹ́ tí ìwé atúmọ̀ alátẹ̀síl ẹ̀ nínú ìwé ti wà lédè Yorùbá. Lára wọn ni: Crowther (1852); Bowen (1858); Delanọ (1958); Abraham (1958); Delanọ (1969); àti Adewole (2005). Nítorí náà, lójú tó mọ́ lónìí yìí, ohun iyì àti ẹ̀yẹ ni kí èdè tó ti gbèrú ní ìwé atúmọ̀ èdè ajẹmẹ́rọ yàtọ̀ sí èyí tí a tẹ̀ sínú ìwé tí a ṣe ẹ̀kàrìkà wọn sókè. Ẹ rántí wí pé bí a ti ń kọ́ èdè yìí nílé, ni a ń kọ nílẹ̀ òkèèrè; bí àwọn onímọ̀ tí wọ́n jẹ́ ọmọ Yorùbá ti wà ni àwọn tí kì í ṣe elédè Yorùbá ṣùgbọ́n tí wọ́n jẹ́ onímọ̀ èdè Yorùbá. Nítorí náà, gbogbo ohun tí a bá ń ṣe lónìí tí kò bá ti ní ọwọ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ nínú kò pé. Àpẹẹrẹ àwọn ìwé atúmọ̀ èdè ní èdè Yorùbá tí a ti fi ẹ̀rọ gbé jáde ni Yoruba Dictionary app, English Yoruba Dictionary, Yoruba Dictionary Offline, abbl.

**4.2 Ẹ̀rọ Akọ́ni ní Èdè Yorùbá**
Ọ̀kan lára àwọn ète tí wọ́n ń pa lóde òní ní kíkọ́ni ní Yorùbá ni ìṣàmúlò àwọn ẹ̀rọ tí ó lè lo áàpù ìkọ́ni ní èdè abínibí. Àpẹẹrẹ irú àwọn áàpù tí a ń ṣe alábápàdé ìkọ́ni ní èdè Yorùbá ni áàpù Muta, Memrise, Yoruba101, SpeakYoruba, abbl. Ohun ìwúrí ni ó jẹ́ pé irú àwọn áàpù ìkọ́nilédè báyìí wà lédè Yorùbá.

**4.2.1 Memrise**
Mẹmẹráìsì (Memrise) jẹ́ èròjà áàpù ìkọ́nilédè kan pàtàkì. Ọ̀nà àgbàmúṣẹ́ṣe rẹ̀ ni ìkọ́nlédè onífikùnlukùn àti ṣeékári tí ó máa ran àwọn tó ń ṣe àmúlò rẹ̀ lọ́wọ́ láti lè kọ́ èdè tuntun. Àmúlò áàpù yìí wà nínú ẹ̀rọ Áńdúrọ́ọ̀dì àti àwọn ẹ̀rọ kọ̀npútà gbogbo. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè bí Kòríà, Jàpaní, Jámánì àti Pọ̀nyán, Faransé, Turkish, Italian, Chinese, Dutch, Pọtọgí, Russian, Swedish, Norwegian, Polish, Danish, Slovenian, Icelandic àti Yorùbá, ló ti ń ṣe àmúlò áàpù náà báyìí. Lára àwọn ohun pàtàkì tí áàpù yìí wúlò fún tó sì ń ṣe àmúlò ni ọ̀rọ̀-èdè, pípèjáde-tó-dán-mọ́rán, gbígbọ́, àti sísọ èdè nípa oríṣiríṣi ẹ̀kọ́ tí a gbé kalẹ̀ láti máa gbé ìjíròrò abáyému jáde. Memrise tún máa ń pèsè fídíò tí a ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ ojúlówó àwọn ọmọ Yorùbá tó gbédè tí wọ́n sì mọ àṣà; àní àwọn tó ń ṣe àmúlò èdè yìí lójoojúmọ́. Áàpù yìí máa ń mú kí ẹni tó fẹ́ kọ́ èdè yìí ní òye ojúkojú. Ní ìkádìí, ọ̀fẹ́ ni ìlò áàpù yìí bá dé. A lè ri sọ̀kalẹ̀ (download) lórí ìtàkùn ayélujára.

**4.2.2 Duolingo**
Ọ̀kan lára àwọn áàpù ajẹmédè tún ni Duolingo. Gẹ́gẹ́ bí ti àwọn mìíràn, ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ èdè ló ń ṣe àmúlò rẹ̀ fún kíkọ́ èdè lábala ìdánrawò ní sísọ, kíkà, gbígbọ́, dídẹtísí àti kíkọ láti ní ìmọ̀ kíkún nípa èdè tí ènìyàn bá yàn láyò. Lára àwọn èdè tó ń ṣe ṣe àmúlò Duolingo ni Jàpaní, Jámánì àti Pọ̀nyán, Faransé àti àwọn èdè mìíràn tí kíkọ́ wọn kò fi bẹ́ẹ̀ wọ́pọ̀ b.a. High Valyrian àti Klingon. Àǹfàní pàtàkì ni áàpù yìí jẹ́ fún mùtú mùwà nítorí ọ̀fẹ́ ló bá dé.

**4.2.3 Yoruba101**
Yoruba101 jẹ́ áàpù kan tó máa ń bá Android ṣiṣẹ́ fún àmúlò kíkọ́ èdè Yorùbá nìkan láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Ní pàtàkì, áàpù yìí wà fún kíkọ àwọn ọmọdé ní ẹ̀kọ́ Yorùbá lọ́nà gbẹ̀fẹ́ àti èyí tó fún wọn ní àǹfàní àtikópa nínú ẹ̀kọ́. Gẹ́gẹ́ bí olùdásílẹ̀ rẹ̀, Ọ̀gbẹ́ni Adébáyọ̀ Adégbémbọ̀ ti sọ́ di mímọ̀, àwọn àgbà tí kì í ṣe ọmọ Yorùbá ṣùgbọ́n tí wọ́n bá fẹ́ ẹ́ kọ́ èdè Yorùbá ní pele ìpìlẹ̀ lè jẹ àǹfàní áàpù yìí.

**4.2.4 Live Lingua**
Live Lingua ni áàpù mìíràn tí ó máa ń pèsè ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Yorùbá ní ọ̀fẹ́. Lára àwọn èròjà tí ó máa ń pèsè ni àwọn ìwé inú afẹ́fẹ́ (ebooks) àwọn fáìlì àfetígbọ́ (audio files). Èyí mú kí ó rọrùn fún akẹ́kọ̀ọ́ láti lè dá kọ́ ara rẹ̀. Àwọn èròjà ìkọ́ni orí ìkànnì yìí lọ tàárà, èyí tó mú kí àwọn alákọ́bẹ̀rẹ̀ le fúnra wọn ní ìpìlẹ̀ tó dán mọ́rán tédè tí ènìyàn ń kọ́ fi máa yéni yékéyéké.

**4.2.5 Yorùbá Yé Mi**

Yunifásítì ti Texas ní ìpínlẹ̀ Austin ní orílẹ̀ èdè Amẹ́ríkà ni a ti kọ̀ ìwé tó wà ní Online tí a mọ̀ sí Yorùbá Yé Mi. Ìwé yìí pèsè àtò àti àkóónú tó péye fún ẹ̀kọ́ Yorùbá. Ìwé náà dára gbáà fún àwọn tó jẹ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ àti àwọn tó tẹ̀lé wọn. Ohun tó jẹ́ àkóónú ìwé náà ni gírámà, ìró ohùn àti ohun àmúṣagbára fún ìbáraẹnisọ̀rọ̀. Ìkànnì ayélujára tí a ti lè ba pàdé ni Yorùbá Yé Mi.

**4.2.6 YorubaLessons.com**

YorubaLessons.com tún jẹ́ ìkànnì orí afẹ́fẹ́ kan tó wà fún ìkọ́raẹni ní oríṣiríṣi ẹ̀kọ́ Yorùbá. Ìlànà rẹ̀ mú kí ọ́ rọrùn fún ìdára-ẹni-kọ́ tí olórí pípé akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ gbékalẹ̀ pẹ̀lú ọgbọ́n ìkọ́ni ní ọ̀kanòjọ̀kan ẹ̀kọ́ tó jẹ mọ́ ohun tí í ṣe Yorùbá. Àgbékalẹ̀ àwọn kọ́ọ̀sì (ẹ̀kọ́) pẹ̀lú àtò tó péye àti àwọn ẹ̀kọ́ tó bójú mu mú kó wúlò fún àwọn tó ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ láti fà wọ́n ní tẹ̀ẹ́tẹ́ títí dé ipò tí wọ́n fi lè sọ èdè Yorùbá dán mọ́ránmọ́rán.

**4.2.7 MyLanguages.org**

Ìkànnì ayélujára kan tó tún ṣe ìgbéga fún ẹ̀kọ́ Yorùbá ni MyLanguages.org. Ìkànnì ayélujára yìí rọrùn fún àmúlò àwọn tó ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí kọ́ Yorùbá ní ìpele bí a ṣe ń pe ọ̀rọ̀, gírámà àti àmúlò ìkójọ àti ìtúmọ̀ ọ̀rọ̀. Orísun to dára gan-an fún àwọn tó bá ṣẹ̀ṣẹ̀ féẹ́ bẹ̀rẹ̀ lọ́nà tí ó fi lè dé pele ẹni tó lè tójú bọ́ ni ìkànnì yìí.

**5 Ọṣẹ́ tí Àmúlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ń ṣe èdè Yorùbá**

Bó ti ládùn ló léwu, egungun ẹja ni ọ̀rọ̀ àmúlò ìmọ̀ ẹ̀rọ àti Yorùbá jẹ́. Àwọn ohun tí mo gbèyẹ̀wò ní 4.2 ni ó ṣeé tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí àmúyẹ fún lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ láti ṣe ìgbélárugẹ èdè Yorùbá. Àmọ́ sáá, àwọn àkíyèsí kan tí mo ti ṣe fi hàn pé, ewu ń bẹ lóko Lóńgẹ́, Lóńgẹ́ fúnra rẹ̀, ewu ni. Bẹ́ẹ̀ ni ti àwọn ìṣòro tó rọ̀ mọ́ oríṣiríṣi ìmọ̀ ẹ̀rọ tí mo ti fi hàn lókè. Ẹ jẹ́ ká wo díẹ̀ nínú àwọn ìṣòro náà.

**5.1 Ẹ̀rọ àti àwọn èròjà inú wọn**

Gẹ́gẹ́ bí mo ti fi hàn ṣáájú, ẹ̀rọ méjì tó ṣe pàtàkì tí àwọn ènìyàn ń ṣe àmúlò rẹ̀ fún kíkọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá ní ọ̀nà ìgbàlódé ni kọ̀ǹpútà àti fóònù. Èyíkéyìí wọn ni wọ́n ti fi ń dábírà pẹ̀lú oríṣiríṣi áàpù. Ìṣòro kan tó rọ̀ mọ́ àmúlò ẹ̀rọ wọ̀nyẹn láti kọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá àti àmúgbòòrò rẹ̀ ni àìsíní-àrọ́wọ́tó olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́. Àìsíní-àrọ́wọ́tó yìí kì í ṣe ti àìsí rẹ̀ lórí àtẹ bí kì í ṣe ọ̀dá owó láti rà wọ́n fún ọ̀pọ̀ olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́.

**5.2 Olùkọ́ tàbí atọ́nà lórí ìtàkùn àgbáyé**

Irú wá, ògìrì wá, ni olùkọ́ orí ìtàkùn àgbáyé. Èkó gbolè, ó tún gbọ̀lẹ ni pẹ̀lú. Àtàwọn tó lóye àtàwọn ọ̀gbẹ̀rì ló ń patú ọwọ́ wọn láìbèṣù, bẹ̀gbà, nítorí kò sẹ́ni to lè kúkú yẹ̀ wọ́n lọ́wọ́ wò, débi tí wọ́n máa ká wọn lọ́wọ́ ọ̀hún kò. Àwọn tí a mọ̀ tó kúnjú owó wà, àwọn tí a mọ̀ tí wọn kò fi bẹ́ẹ̀ kúnjú òṣùwọ̀n náà wà lọ́pọ̀ yanturu. Lára àwọn tí wọ́n ń gbìyànjú gidi lóri ìkànnì ayélujára ni Ọ̀mọ̀wé Adébáyọ̀ Taofeeq tó wà ní California tó ń ṣe agbátẹ̀rù kíkọ́ni nípa sáyẹ́ǹsì àti àmúgbòòrò rẹ̀ ní èdè Yorùbá.

Àmọ́ sáá, gẹ́gẹ́ bí ohun tí mo ṣe àwárí rẹ̀ lórí ìtàkùn àgbáyé, ìkànnì kan wà tí a mọ̀ sí **Digital Yoruba** tí olùkọ́ kan ń gbà kọ́ni ní ẹ̀kọ́ Yorùbá lọ́nà òdì, pàápàá ní abala èdè àti lítíréṣọ̀. Orúkọ olùkọ́ yìí ni Ọ̀gbẹ́ni Dèjì Ọláiyá. Ó ṣe àgbékalẹ̀ oríṣiríṣi ẹ̀kọ́ lórí Yorùbá lápapọ̀. Ọ̀kan nínú wọn ni ẹ̀kọ́ lórí ọ̀rọ̀-ìṣe tó pín sí adọ́gba'regular' àti alàìdọ́gba 'irregular verbs'. Ohun káyéfì àkọ́kọ́ ni ìpínsísọ̀rí rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí àpẹrẹ, àkíyèsí mi nípa àbùdá àwọn ọ̀rọ-ìṣe adọ́gba ní èrò tirẹ̀ ni wí pé, wọ́n parí pẹ̀lú kọ́ńsónáńtì!

(1) Regular verbs
  a. sa**n** ‘to pay’
  b. sa**n** ‘to crack’
  d. sa**n** ‘to heal’

Ohun méjì pàtàkì ló gba àkíyèsí nípa èrò rẹ̀ yìí o. Ohun àkọ́kọ́ ni pípé kọ́ńsónántì ‘**n**’ tí a fi ń ṣe àmì ìránmú fún fáwẹ̀lì aránmúpè ní kọ́ńsónántì aránmúpè sànán.[3] Káyèfí ńlá gbáà ni. Àwòṣe ọ̀jẹ̀, kò lè dà bí Ọ̀jẹ́làdé, tó bá jẹ́ ọmọ abílọ́jẹ̀, ìbá mawoó ṣe. Dájúdájú, Ọ̀gbẹ́ni Dèjì kò ní ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè rárá, bẹ́ẹ̀ ni òye fónẹ́tíìkì àti fonọ́lọ́jì Yorùbá kò ye rárá. Tí a bá kọ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe wọ̀nyẹn ní àdàkọ fónẹ́tíìkì bí mo ti ṣe yìí: [sã], ṣe ni ‘n’ yẹn máa pòórá. Ohun kejì tó ṣe ni ní kàyéfì ni wí pé, yàtọ̀ sí àìlóye fonọ́lọ́jì Yorùbá rẹ̀ tó fi sọ kọ́ńsónáǹtì ìṣàmì ìránmú di ojúlówó kọ́ńsónántì tó pẹ̀kun àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyẹn, pípín ọ̀rọ̀-ìṣe sí adọ́gba àti aláìdọ́gba tún jẹ́ ìṣìnà pátápátá. Yorùbá kò ní àbùdá yẹn fún àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe Yorùbá. Ẹ jẹ́ kí a wá wo àpẹrẹ ọ̀rọ̀-ìṣe rẹ̀ tó pè ní aláìdọ́gba (2) àti bí ó ṣe sọ wọ́n di adọ́gba.

(2) Irregular verbs
  a. jẹ, jẹ́, jẹ̀
  b. já, jà
  d. bù, bú, bu[4]

Láti sọ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe wọ̀nyẹn tí ó pè ní aláìdọ́gba di adọ́gba, àtúnrọ tó ṣe fún wọn ló wà nísàlẹ̀.

(3) a. je**s**, jel, je**r**
  b. ja**r**, ja**l**
  d. bu, bu**l**, bu**r**

Ní àkọ́kọ́, kò yán ‘ẹ’ inú (3a) nídìí. Lọ́nà kejì, kò sí èyíkéyìí àpẹrẹ tó wà ní (2) tó yẹ kó ní àmì ìró ohùn òkè tàbí ìsàlẹ̀ tó fi àmi wọ̀nyẹn sí. Lọ́nà kẹ́ta, láti mú kí àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe yẹn di adọ́gba nínú òye tirẹ̀, dandan ni kí wọ́n parí pẹ̀lú kọ́ńsónántì gẹ́gẹ́ bó ti hàn ní (3). Wàyí o, tí a bá farabalẹ̀ wo àwọn àpẹrẹ wọ̀nyẹn, yàtọ̀ sí àìyán fáwẹ̀lì ‘ẹ’ àti àìfi àmì ìró ohùn sórí àwọn ọ̀rọ̀ yẹn, ó tún wá pa kádàrá àwọn ọ̀rọ̀ yẹn dà nípa fífi kọ́ńsónántì pẹ̀kun àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe kọ̀ọ̀kan, èyí tó tako ìhun sílébù àti ọ̀rọ̀ Yorùbá. Kò tán síbẹ̀. Tí a bá wo àwọn àpẹrẹ (3), tí Ọ̀gbẹ́ni Ọláìyá ti ṣe àtúnrọ wọn, yàtọ̀ sí àwọn àlébù ìlànà àkọsílẹ̀ tí mo ti fi hàn, ohun kan tó kù kí n fi hàn ni irúfẹ́ kọ́ńsónáǹtì tó yàn láyò láti fi pẹ̀kun àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe wọ̀nyẹn. Kọ́ńsónántì mẹ́ta: “l”, “r” àti “s” ló yàn láyò! Ìbéèrè àkọ́kọ́ ni: nínú kọ́ńsónántì méjìdílógún ti èdè Yorùbá ní, kí ló jẹ́ ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ tó fi yan àwọn mẹ́ta wọ̀nyẹn gẹ́gẹ́ bí kọ́ńsónáǹtì àmúpẹ̀kun? Ìbéèrè mìíràn ni, kí ni àjọṣepọ̀ tó wà láàárin àwọn kọ́ńsónántì mẹ́ta náà tàbí àbùdá tó pa wọ́n pọ̀? Àbùdá ajẹmọ́fónẹ́tíìkì kan tí mo rí tó pa wọ́n pọ̀ ni pé àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta jẹ́ kọ́ńsónáǹtì àfèrìgipè. Ṣùgbọ́n ìyẹn gan-an tún fa ìbéèrè mìíràn: kí ló fà á tí kò fi yan “t”, “d” láyò gẹ́gẹ́ bí kọ́ńsónántì àmúpẹ̀kun? Ó tún ku ìbéèrè kan o. Kí ló fà á kí ó tó fi “s” pẹ̀kun “je” kan, “r” pẹ̀kun “jẹ” mìíràn tó wá fi “l” pẹ̀kun “je” kan tókù? Àìrí àpẹrẹ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe mìíran tàbí ọ̀rọ-orúkọ kò jẹ́ kí a mọ̀ bóyá ó tún ṣe àfikún àwọn kọ́ńsónáǹtì mìíràn.

Ohun kejì tí iṣẹ́ rẹ̀ tí mo ṣe alábàpàdé jẹ mọ́ ni ó pè ni ‘Digital Yorùbá orthography’. Nínú ìfáárà rẹ̀, ó béèrè pé ‘kí ni ó ń jẹ́ Díjítà Àkọtọ́ Yorùbá? Ó sì fi fúnra rẹ̀ dáhùn wí pé:

> Digital Yoruba is an Alternative Orthography for Yoruba Language or simply, a new, innovative way to write Yoruba. It is based on alphabetic separation of similar words

[3] Wo Ajiboye (2024) fún oríṣi kọ́ńsónántì “n” mẹ́ta tó wà ní Yorùbá.

[4] Ẹ ṣe àkíyèsí wí pé, àwọn àpẹrẹ òkè kó ní àmì ìró ohùn nínú àgbékalẹ̀ rẹ̀.

rather than accents. It is much easier to write and learn since every word is written differently in a scientific, logical order. Digital Yoruba repackages, rebrands and beautifies Yoruba Language to make it very reader friendly, endearing and attractive to our new generation, and to those in the Diaspora. (http://wwwdejiolaiya.com)

Díjítà Yorùbá jẹ́ ààrọ̀ fún àkọtọ́ Yorùbá, abí ká kúkú sọ pé ọ̀nà ọ̀tun tí a lè gbà kọ Yorùbá sílẹ̀. Ìlànà yìí gùn lé yíya álífábẹ́ẹ̀tì àwọn ọ̀rọ̀ tí lẹ́tà wọn bá jọra sọ́tọ̀ dípò ìró ohùn. Ó rọrùn láti kọ àti láti kọ́ nítorí a kọ irú ọ̀rọ̀ tí wọ́n jọra bẹ́ẹ̀ ní ọ̀nà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ lọ́nà tó jẹ mọ́ sáyẹ́nsì àti àtò alárògún. Díjítá Yorùbá ṣe àtúndì, àtúnṣe, ó sì fi kún ẹwà èdè Yorùbá láti mú kó rọrùn ní kíkà kó sì fanimọ́ra fún àwọn mọ̀jèsín àsìkò yìí àti àwọn tó wà nílẹ̀ àjòjì.

Ajá Òyìnbó dára, ó ku àtiṣọdẹ. Tí a bá wo àyọlò òkè, láríjà olùkọ́ yìí ni ọ̀nà láti mú kíkọ́ àti kíkọ Yorùbá sílẹ̀ rọrùn. Àmọ́ sáá, ohun tí a rí mú bọ̀ burú, kódà ó bògìrì, ó kọjá ìnira, ṣe ló da ohun tí a mọ̀ mọ bí a ti ń kọ Yorùbá sílẹ̀ rú pátápátá.

Ní ìkádìí, mo mú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí wá láti inú ìwé ìtàn àròsọ rẹ̀ kan láti rí ìtọ́wò ohun tí ó ti ṣe sí àkọtọ́ Yorùbá nínú lítíréṣọ̀:

Arobba Lerefe
Lara Sopitan - arewwall obinrin, elleyyinju eggell, ati arimalehelort tous ferront ivadunt..Iwerohin soppeas Lara coou sinoon tuboou l'Hecour, shuvorn lehhin ossess melocon, Lara voriwolle si ivoro London. Sibert sibert, lassivo Lara shezzell berrell nin.

Mo gbìyànjú láti ṣe àtúnkọ rẹ̀ kí a lè rí ibi tí òǹkọ̀wé da orí èdè Yorùbá kọ.

Àrọ́bà Léréfèé
Lará Ṣópìtàn - arẹwà obìnrin, ẹlẹ́yinjú ẹgẹ́, àti àrímáleèlọ tó sì fẹ́ràn ìgbádùn..Ìwé ìròhìn sọ pé Lará kó sínú túbú l'Ékòó, ṣùgbọ́n lẹ́hìn ọ̀sẹ̀ mélòó kan, Lará gbórí wọlé sí ìgboro Lọ́ńdọ̀nù. Síbẹ̀ síbẹ̀, làásìgbo Lará ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ni…

Ẹ̀yin tó ń ka pépà yìí fúnra yín lè sọ ibi tí Ọ̀gbẹ́ni Ọláìyá àti ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ẹlẹ́gbẹ́ rẹ̀ fẹ́ ẹ́ dá Yorùbá padà sí; ẹsẹ̀ ààrọ̀, ìyẹn àkókò àkọsílẹ̀ ayé Samuel Àjàyí Crowther! Ṣé ó dáa bẹ́ẹ̀? Àìláṣọ lọ́rùn pàràká, ohun àpérò maríwo ni.

**5.3 Àìkúnjú-òṣùwọn àwọn ààpù àmúlò fédè Yorùbá**

Gẹ́gẹ́ bí a ti tọ́ka si lókè, ọ̀pọ̀ ààpù ló ti wà láti fi kún ìmọ̀ olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ọ̀fẹ́ ni a lè rí díẹ̀ wọn lò, àwọn kan wà tó jẹ́ wí pé a gbọ́dọ̀ lówó lọ́wọ́ kí a tó lè rí wọn rà, kí a sì tó lè lò wọ́n lórí ẹ̀rọ. Yàtọ̀ sí ìṣòro yìí, àwọn ààpù kan wà tí kò kúnjú òṣùwọn tó láti kọ́ni ní ohun tí wọ́n wà fún. Ìṣòro mìíràn tó ń kojú èdè Yorùbá ni ti ààpù atúmọ̀ èdè, bóyá títúmọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì sí Yorùbá àbí títúmọ̀ èdè Yorùbá sí èdè mìíràn. Àkíyèsí mi ni wí pé, àkóónú ààpù wọ̀nyí kò kún tó ní abala àká ọ̀rọ̀, àpólà àti gbólóhùn. Ohun méjì ni àyọrísí kùdìẹkudiẹ yìí mú wá. Èkíní, àwọn ọ̀rọ̀ kan kò ní ojúgbà ní èdè tí a fẹ́ túmọ̀ rẹ̀ sí. Èkejì ni wí pé ìtúmọ̀ òdì tàbí ìtúmọ̀ tí kò béti mu ni wọ́n máa ń gbé jáde nígbà mìíràn.

**6 Ìgúnlẹ̀**

Kí n tó dánu dúrò, gbogbo olùkọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá láti ilé ìwé alákọ́bẹ̀rẹ̀ títí dé Yunifásítì, àwọn ẹgbẹ́ bí akọ́mọlédè àti àṣà, ẹgbẹ́ onímọ̀ Yorùbá àti àwọn olùfẹ́ ohun gbogbo tí í ṣe ti Yorùbá ni ó gbọ́dọ̀ tún ṣòkòtò wọn sán láti kojú ìṣòro àti ọṣẹ́ tí àmúlò àwọn ẹ̀rọ àti oríṣiríṣi ààpù ti bẹ̀rẹ̀ sí ń ṣe èdè náà

lọ́wọ́lọ́wọ́. Ní ìgúnlẹ̀, mo wá ń pàrọwà sí ìjọba, àwọn lájọlájọ, àti àwọn ilé ìwé, bóyá ti ìjọba àbí àdáni láti ṣe àtìlẹyìn tó péye, fún ìpèsè àwọn èròjà ẹ̀kọ́ túntun wọ̀nyí ní ilé ìwé gbogbo láti mú kí kíkọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá túbọ̀ rọrùn, kó sì gbòòrò si. Àwa tí a jẹ́ olùkọ́ sàn-án náà kò gbọ́dọ̀ sun àsùnpiyè lórí ohun tó ń lọ lórí ìkànnì ayélujára nípa bí kíkọ́ àti kíkọ èdè Yorùbá ti di irú wá, ògìrì wá. Tí a bá ń sọ pé Yorùbá kò gbọdọ̀ kú, pé kò sì ní í kú, ọ̀rọ̀ náà kọjá àfisorinkọ nìkan. Yorùbá kíkọ́ àti kíkọ wà nínú ewu. A sì gbọ́dọ̀ ṣetán láti yọ kúrò nínú ewu náà ní kíákíá.

**Ìwé Ìtọ́kasí**


A Dictionary of the Yoruba Language. 1913. Church Missionary Society Bookshop, Lagos

Abraham, Royce Clif. 1958. Dictionary of Modern Yoruba. University of London Press.

Adewole, L.O. 2005. A Bilingualized Dictionary of Yorùbá Monosyllabic Words. Montem Paperbacks, Akure, Nigeria.

Bowen, T.J. 1858. Grammar and Dictionary of the Yoruba Language. Smithsonian Institution. New York.

Crowther, Samuel. 1852. Grammar and Vocabulary of the Yoruba Language. Seeleys, Hanover Square, London.

Delanọ, Isaac. 1958. Atúmọ̀ Ede Yorùbá. Oxford University Press. London.

Delanọ, Isaac. 1969. A Dictionary of Yoruba Monosyllabic Verbs. Institute of African Studies, University of Ife.